# IṢỌKAN IJỌ KRISTI

## Efesu 3:14-21; 4:1-16

## ẸKỌ 402 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Nitorina emi ondè ninu Oluwa, mbẹ̀ nyin pe, ki ẹnyin ki o mã rin bi o ti yẹ fun ipe na ti a fi pè nyin" (Efesu 4:1).**

**I Adura Apọsteli naa fun Awọn Ara Efesu**

1 Lati di alagbara ninu ọkunrin ti inu, Efesu 3:14-16; Romu 9:23; 2 Kọrinti 4:16; Kolosse 1:11, 27

2 Pe ki Kristi le maa gbé inu ọkàn wọn nipa igbagbọ́, Efesu 3:17; Johannu 14:23

3 Lati mọ titobi ifẹ Ọlọrun, Efesu 3:18; 1:18; Romu 10:12

4 Lati ni gbogbo ẹkunrẹrẹ Kristi, Efesu 3:19; Heberu 13:21; Johannu 1:16

**II Ọrọ Iyanju fun Iṣọkan Awọn Onigbagbọ́**

1 Irin yiyẹ ṣe danindanin fun ipe giga Onigbagbọ́, Efesu 4:1; Filippi 1:27; 1 Tẹssalonika 2:12

2 Eso ti Ẹmi maa n fara hàn ninu iwa wa pẹlu ara wa, Efesu 4:2; Iṣe Awọn Apọsteli 20:19; Galatia 5:22, 23; Kolosse 3:12, 13;

3 A maa n pa iṣọkan Ẹmi mọ́ ninu idipọ alaafia, Efesu 4:3; Johannu 14:27; Kolosse 3:14

**III Iṣọkan Ohun gbogbo nipa ti Ọlọrun**

1 Ara kan ni Ijọ Kristi. Ẹmi kan ni n bẹ -- Ẹmi ti Kristi, Efesu 4:4; Romu 12:5; 1 Kọrinti 12:11, 12; Heberu 6:19

2 Oluwa kan ni n bẹ -- Jesu Kristi; igbagbọ kan -- Ẹkọ ti Kristi; baptisimu kan – Oun ni O fi ilana yii lelẹ. Efesu 4:5; Matteu 28:19; Galatia 3:27, 28.

3 Ọlọrun kan ni n bẹ ninu ẹni ti awa wà laaye ti a si ni ẹmi wa, Efesu 4:6; Malaki 2:10; Romu 11:36; 1 Timoteu 2:5

**IV Iṣẹ Ijọ ninu Ayé**

1 A fi oriṣiriṣi ẹ̀bun fun awọn eniyan nigba ti Kristi gun oke lọ si Ọrun, Efesu 4:7-10; Orin Dafidi 68:18; Romu 12:6-8; 1 Kọrinti 12:4-11; 1 Timoteu 3:16; Heberu 9:24

2 A yan awọn olukọni lati le mú Ijọ wá si pipe, ati pe ki a má ba fi ẹ̀kọkẹkọ mú awọn ọmọ Ọlọrun ṣina, Efesu 4:11-16; Isaiah 28:9; Heberu 13:9; 2 Timoteu 4:5

### ALAYE

### Ọlọrun Baba Wa

Ẹkọ yii bẹrẹ pẹlu adura Paulu fun awọn ara Efesu. O fi hàn pe akopọ gbogbo ẹbi awọn ẹni-irapada ni Ọrun ati ayé ni a pè ni orukọ fun Baba. Gẹgẹ bi iwa awọn ọmọ-eniyan laaarin ara wọn a kò ha n jẹ́ orukọ mọ́ baba wa ninu ayé ni? Nipasẹ Jesu Kristi a ṣe gbogbo wa ni ọ̀kan ninu ibatan wa pẹlu Ọrun, bi o ba ṣe pe a ti tun wa bi ti a si ti kọ orukọ wa silẹ ni Ọrun. Ọlọrun ki i ṣe Baba awọn wọnni ti wọn kọ Ọmọ Rẹ̀ ati eto Rẹ̀ fun igbala. Jesu sọ fun awọn Farisi pe, "Ti eṣu baba nyin li ẹnyin iṣe, ifẹkufẹ baba nyin li ẹ si nfẹ ṣe" (Johannu 8:44). Ibatan wa pẹlu Ọlọrun ni o mu ki Ọlọrun jẹ Baba wa. Ọlọrun ki i ṣe olupilẹṣẹ ẹ̀ṣẹ bẹẹ ni ki i si i ṣe Baba awọn ti n gbé igbesi-ayé ẹ̀ṣẹ. Bakan naa ni awọn wọnni ki i ṣe arakunrin, ti wọn kọ Arakunrin wa Agba ti wọn si n rin nipa ti ara.

### Ọrọ̀ Ọlọrun

Apa kin-in-ni adura Paulu fun wọn ni pe ki wọn le di alagbara ninu ọkunrin ti inu gẹgẹ bi ọpọlọpọ **ọrọ̀** ogo rẹ̀. Ọrọ̀ Ọlọrun kò ṣee diwọn rara. Ẹbun ọfẹ si ni patakpata. Nigba ti ọlọrọ ba fi ẹ̀bun tọrẹ, a woye pe o yẹ ki o fi ẹbun naa tọrẹ gẹgẹ bi oun ti ni tó. Nigba ti alaini ba si fi ẹbun tọrẹ, eniyan yoo reti pe o gbọdọ jẹ́ ẹ̀bun kekere, nitori pe oun kò ni pupọ lati fi tọrẹ. Ṣugbọn ronu bi ini Ọlọrun ti pọ̀ tó!

Pelupẹlu, Oun tilẹ le ṣe kọja eyikeyi ti awa le rò tabi le beere fun lọ. Kristi, gẹgẹ bi ẹ̀bun fun ọmọ-eniyan jẹ́ iwọn bi ifẹ Ọlọrun ti pọ̀ tó, ati pẹlu, ikú Kristi fun eniyan jẹ́ odiwọn bi ifẹ Rẹ̀ ti tó.

Paulu n fẹ ki Kristi maa gbé inu ọkàn wọn nipa igbagbọ́ ati pe ki wọn ta gbongbo jinlẹ, ki wọn si fi ẹsẹ mulẹ ninu ifẹ, ki wọn ba le mọ ailoṣuwọn ifẹ Ọlọrun.

Onjẹ ti ara ni o n mu ara dagba, ṣugbọn onjẹ atọrunwa ni o n mu ọkunrin ti inu dagba. Lati le wà laaye, awọn mejeeji ni a gbọdọ fi onjẹ bọ́. Ṣá ara ti, yoo kú ni. Ṣá ọkunrin ti inu (ẹmi) ti, oun pẹlu yoo kú. Paulu n fẹ ki wọn mọ ifẹ Kristi, eyi ti a nawọ rẹ̀ si wọn lọpọlọpọ to bẹẹ, ki wọn ba le ni gbogbo ẹkunrẹrẹ Ọlọrun. Ẹni kan ti sọ bayii pe ki Ọlọrun kún inu eniyan jẹ́ nnkan titobi; lati kún fun ẹkunrẹrẹ Ọlọrun tobi jù; ṣugbọn lati ni gbogbo ẹkunrẹrẹ Ọlọrun ta oye eniyan yọ. Eyi ni pe ki a kún fun iwa tutù, iṣoore; iwa pẹlẹ, ifẹ, suuru, iwa ododo, iwa mimọ́, aanu ati jijẹ́ olooootọ. Diẹ ni awọn ti i ṣe apẹẹrẹ iru ẹkunrẹrẹ yii. Iduro ọ̀pọlọpọ eniyan fi hàn pe diẹ kinun ni wọn ni tabi wọn kò tilẹ ni ohun kan rara ninu ẹkunrẹrẹ Ọlọrun.

Paulu gbadura pe ki awọn ara Efesu le ri ibukun ti o ga jù lọ gbà ninu iriri wọn gẹgẹ bi Onigbagbọ́. Njẹ eyi kò ha fi pipe Iyawo Kristi hàn? Ni igba laelae, awọn ọba a maa wá eniyan ti o pé ni ẹwà fi ṣe Iyawo. Ki ni ṣe ti awa ki yoo fi reti pe Kristi wa pẹlu yoo maa wá iru pipé ti ẹmi bẹẹ laaarin Ijọ, Iyawo Rẹ̀ ti yoo ba A rin ni ifẹgbẹ-kan-ẹgbẹ ninu Ijọba Rẹ̀ lori ilẹ ayé yii?

**Irin pẹlu Ikiyesara**

Maa rin yẹ si ipe naa! Bawo ni àye ti a ni lati dé yii ti ga tó? Ninu ọkàn wa, ki ni àye giga ti a ti gbé kalẹ? Njẹ a ha ro bi o ti yẹ lati kún fun iwa tutù, kún fun ifẹ, kún fun ayọ̀, kún fun irẹlẹ, kún fun iwa otitọ tó? Njẹ iru àye giga ti a gbé kalẹ fun awọn ẹlomiran ni a gbé kalẹ fun ara wa bi?

Ori oṣuwọn Ọlọrun ni a o ti wọn pipeye wa, ki i ṣe pẹlu ero tabi aipe wa. Iṣisẹ kọọkan ni ọna ere ije ti igbagbọ́ yii gbọdọ jẹ́ iṣisẹ ti igboya, ti igbagbọ́, ti ifẹ, ti iwa tutù, ti ijẹ-olooootọ si otitọ naa. Eyi ni Oluwa n beere lọwọ wa, yoo dun Un pupọ bi a ba kuna; ati pe nipa ikuna wa a le sọ ipo wa nù gẹgẹ bi Iyawo Kristi.

**Iṣọkan**

"Iṣọkan ni i mu ni duro gbọin ṣugbọn iyapa a maa mú iṣubu wá." Eyi ki i ṣe ọrọ lati inu Bibeli wá ṣugbọn otitọ ni. A gbọ́ itàn nipa baba kan ti o ni ọmọkunrin pupọ. Ni ọjọ kan, o ṣa igi jọ o si di wọn ni ìdì kan; o gbé ìdì igi naa tọ awọn ọmọ rẹ̀ wá pe ki ẹni kọọkan wọn wá tẹ̀ ẹ́ ṣẹ́. Kò si ẹnikan ninu wọn ti o le ṣẹ́ ìdì igi naa. Baba wọn gbé ìdì igi naa, o tú u, o si bẹrẹ si i mú igi wọnyii ni ọkọọkan o n ṣẹ́ ẹ, o n fi hàn pe ninu iṣọkan ni agbára wà.

A gbà wá niyanju pe ki a lakaka lati pa iṣọkan Ẹmi mọ́ ni idipọ alaafia (Efesu 4:3).

Jesu sọ pe ẹnu ọna ọrun apaadi ki yoo le bori Ijọ Rẹ̀. Ki ni ṣe? Ijọ ti o wà ni iṣọkan ni. Awọn ọmọ Ijọ le maa gbé ni Afirika, Amẹrika, Japan, West Indies, ibikibi lori ilẹ ayé; Ijọ kan ṣoṣo ni i ṣe, Ijọ Ajagun nihin ninu ayé. Ni ọjọ kan on yoo di Ijọ Aṣẹgun – Iyawo Kristi.

**Ara Kan**

A fi Ijọ wé ara Kristi. Jesu ni Ori. Olukuluku si jẹ́ ẹya ara ọmọnikeji rẹ̀. Kò si ède-aiyede ninu awọn ẹya-ara eniyan. Gbogbo ẹya-ara ni wọn n ṣiṣẹ ni iṣọkan ti o pé ati ni ifọwọsowọpọ pẹlu ara wọn. Gbogbo wọn wà ni itẹriba ati igbọran pipé labẹ ori. Ninu Ijọ olukuluku gbọdọ maa ṣiṣẹ fun irọra ati imuduro apapọ Ijọ, ki o si maa bu ọla fun Ori, ti i ṣe Kristi. Paulu ninu ọrọ itọni, imọran ati imulọkanle rẹ̀, n dù ú lati fi ọna hàn bi a ṣe le jẹ́ Ijọ pipé.

Oluwa kan ni ó wà -- Jesu Kristi; igbagbọ́ kan fun gbogbo agbaye, igbagbọ́ naa si ni awọn ẹkọ ti a tò jọ ninu Ọrọ Ọlọrun lati ẹnu Jesu Kristi ati awọn Apọsteli; baptismu kan, ọ̀kan naa ti Jesu fi lelẹ nigba ti O wà lori ilẹ ayé nihin; Ọlọrun kan, Baba gbogbo wa, ati Ju ati Keferi, orisun gbogbo ẹda alaaye, Ẹni ti o bori ohun gbogbo.

**Igoke-Re-Ọrun Ati Isọkalẹ Kristi**

"Nigbati o gòke lọ si ibi giga, o di igbekun ni igbekun, o si fi ẹ̀bun fun enia. (Njẹ niti pe o goke lọ, kili o jẹ, bikoṣepe o kọ́ sọkalẹ pẹlu lọ si iha isalẹ ilẹ? Ẹniti o ti sọkalẹ, on kanna li o si ti goke rekọja gbogbo awọn ọrun, ki o le kún ohun gbogbo)." Jesu kan naa yii ti o ni iṣẹgun lori ikú, ọrun apaadi ati iboji ni owurọ ọjọ ajinde ni, goke lọ si ibi giga O si di igbekun ni igbekun. Ninu Orin Dafidi 68:18 a ri i bi Onisalmu ti n sọ nnkan kan naa bi ẹni pe o n ya aworan iṣẹgun awọn ẹgbẹ́ ologun. Ati pẹlu ninu Awọn Onidajọ 5:12 a ka pe "Jí, ji, Debora; Jí, jí, kọ orin: dide, Baraki, ki o si ma kó awọn igbekun rẹ ni igbekun."

Ni igba laelae aṣẹgun maa n la ilu já pẹlu awọn igbekun rẹ̀ ti a so mọ́ kẹkẹ rẹ̀ lẹyin; laaarin iyẹsi awọn eniyan, a maa sọ ẹ̀bun si wọn lati inu ikogun rẹ̀. Jesu sọkalẹ wá ninu ayé bi Ọlọrun ninu eniyan, O si fara da iyọṣutisi ati ẹ̀gan awọn eniyan, a kan An mọ́ agbelebu, a si sin In si iboji ṣugbọn eyi ki i ṣe opin. O jinde O si goke lọ si Ibi Giga kọja gbogbo awọn ọrun, ki Oun le mu ohun gbogbo ṣẹ.

**O fi Ẹbun fun Eniyan**

"O si ti fi awọn kan funni bi apọsteli; ati awọn miran bi woli; ati awọn miran bi ẹfangẹlisti, ati awọn miran bi oluṣọ-agutan ati olukọni." Jesu n wo ẹ̀bun atọrunwa awọn ẹya Ara Kristi, O si n ṣe ipinfunni gẹgẹ bi agbára olukuluku. A n ṣe eyi fun isọdi-pipé awọn eniyan mimọ́.

Gẹgẹ bi a ṣe ni ile-ẹkọ ibi ti a ti n kọ́ awọn ọmọ wa ni ẹkọ́ ti aye, bakan naa ni ijọ gbọdọ ni awọn oluṣọ-agutan, ẹfangẹlisti, ati olukọni lati maa kọ́ awọn Onigbagbọ ni ọna ododo ati lati mú wọn dagba ninu igbagbọ mimọ́ nla yii. Awọn ti wọn kò yatọ si ọmọde ni a maa n gbá kiri lati inu ẹkọ́ kan si omiran ki wọn to fi ẹsẹ mulẹ ninu otitọ. Nigba ti wọn ba si ti dagba ti wọn si ti di akọni ọkunrin ati obinrin ninu igbagbọ́, wọn yoo le mọ̀ iyatọ laaarin otitọ ati ẹ̀ké.

A fi awọn olukọni wọnyii fun wa ninu Ihinrere ki a ba lè di akọni ọkunrin tabi obirin ninu Kristi Jesu – ti a so pọ̀ ṣe ọ̀kan ninu Ijọ pipé.

## AWỌN IBEERE

1 Darukọ awọn nnkan diẹ ninu eyi ti Paulu gbadura fun awọn ara Efesu.
2 Bawo ni ifẹ Ọlọrun si eniyan ti tobi tó?
3 Bawo ni Onigbagbọ́ ṣe ni lati kiyesara tó ninu irin rẹ̀?
4 Darukọ diẹ ninu awọn ẹ̀bun ti Jesu fi fun eniyan.
5 Njẹ gbogbo eniyan ni o le pe Ọlọrun ni Baba wọn?
6 Ki ni n mu iṣọkan wá saarin Ijọ?
7 Sọ bi Paulu ṣe fi Ijọ wé ara.
8 Ta ni i ṣe Ori?